# IROHIN LATI AGBEGBE

IWOYE
## AWỌN ỌMỌ IWOYE ṢE IPADE KINI

Awọn ọmọ ilu Iwoye ṣe ipade kini ni ọjọ kọkandinlogun si ọjọ kọkanlelogun osu August ọdun yi.

Ipade na ṣe pataki tobẹ ti gbogbo awọn ọmọ Iwoye to wa ni idale ran aṣoju wa lati orişirişi ilu bi Portharcourt, Enugu, Onitsha, Sapẹlẹ, Jos, Kaduna, Mina, Lagos, Ibadan ati ni ọpọlọpọ awọn ilu gbogbo.

Ohun pataki ti nwọn fi da ipade na silẹ ni fun idagbasoke ati ilọsiwaju ilu Iwoye. Gbogbo eto ti wọn ṣe ni ipade na ni o mu işiri wa tobẹ gẹ ti nwọn ko owo bi adọjọ poun (£150) jọ larin ipade na fun anfani ati ilọsiwaju ilu Iwoye. Ati papa fun awọn ọmọ ilu Iwoye ti ori wọn ba rọ si ẹkọ lati le ṣe iranlọwọ fun iru awọn ọmọ bẹ.

Alaga ipade na ni Ọgbẹni J. O. Ibitayọ Catekist Ilerin, J. O. Onibokun Gidi komọla ni oluranlọwọ kini. oluranlọwọ keji ni Ọgbẹni S. O. Ọfiran, Olubẹwo awọn Ileiwe ni Oşogbo. J. O. Ọla Onibokun ni akọwe ọjọ na. Ọgbẹni T. A. Opẹmuyi ati G. O. Ikọtun ni Oluşeto ipade na.

---

## ỌRỌ LORI ỌNA ILU OLD-IKEJI
(Lati ọwọ Ọgbẹni Josiah Ọlatunji Ibadan)

Mo tọrọ gafara lọwọ Olotu Irawọ Obokun lati sọrọ diẹ lori ọna ilu Old Ikeji yi. Mo bẹ gbogbo ẹnyin Ọba, Ijoye ati Kansẹlọ ati ojulumọ gbogbo Ijẹşa pe ki ẹ jọwọ ki ẹ ba wa tun ọna wa şe, (ọjọ Tawo ti pẹ l'Eko).

Ọjọ ti pẹ ti iya nla a kekere, ti eyi ti o yẹ, ati eyiti ko yẹ, ti nje awọn ara ilu yi. Kini kan wa ya mi lẹnu, iyẹn na nipe gbogbo ilu ti o fi ori wọ si abẹ Ijẹşa, ti nwọn ti nri orişirişi nkan ti o wulo gẹgẹbi koko, ekoro, pako ati orişi nkan miran bi ẹni ti a fi nsun, ilu yi ni koko pupọ ati awọn nkan miran. Şugbọn lai si ọna ti motọ yio gba de ibẹ lati ko, eyi ma je idamu gidigidi fun awọn ara ilu yi o.

Ati ọkunrin ati obirin wọn lo mọ nipa işẹ agbẹ, bẹni ọmọ ko le da nkan şe lẹhin baba rẹ, a si fi ara wa si abẹ nyin gẹgẹ bi ọmọ ti kere si baba rẹ, ọrọ na ku diẹ ki o rọgbọ o.

Gbogbo awọn ilu ayika miran gbogbo ni a nri. Kini ẹşẹ wa si nyin? Bi o ba jẹ bi ẹşẹ ni ki ẹ forijì wa, ki ẹ ba wa şe ọna wa o. Awa na fẹ dabi awọn ilu pataki gbogbo.

Ẹ jọwọ ẹ jẹki awa na ma jẹ lara anfani nyin o ọpọlọpọ ilu kekeke miran wa ti nwọn ko ju idaji ilu Ikeji (Old) yi ti nkan nlọ nibẹ dede bẹni ẹniti o ba de ilu yi ni yio mọ bi nwọn ti pọ to.

Awọn nkan miran wa ti a fẹ tọrọ şugbọn ẹ ba wa şe eleyi şaju o, Ẹwu wa, fila wa, şokoto wa owe ni mo fi pa fila ni a tọrọ bayi o. Ẹ ba wa şe o.

Ẹ fi eyi si ero ọkan nyin lati şe fun wa ki Ọlọrun Olodumare da ile ati ọna nyin si o.

---

IFẸWARA
## IFẸWARA SE ỌDUN ỌLỌJỌ

Odidi ọjọ meji niwọn fi şe ọdun ọlọjọ ni Ifẹwara ni ọdun yi lati ọjọ kẹtala oşu to koja ni wọn ti bẹrẹ ere tiwọn si şere na mọju ọjọ kẹrinla oşu na.

Ọni Ifẹwara, Oloye Adetọna ati awọn oloye rẹ pẹlu awọn ogunlọgọ enia lọ si oke Imogun pẹlu ijo ati ilu Bakanna ni nwọn tun lọ nigbakeji lọjọ kẹtadinlogun oşu na.

Gbogbo oloye ati ara ilu Ifẹwara lo şe ọpọlọpọ inawo aşeyẹ ọdun na.

---

## ISẸ KANSELỌ NI GBỌNGAN
(Lati ọwọ A$_{w}$oko Ọlọoniyọ)

Inu mi dun lati şe alaye lori işẹ aibojumu awọn kansẹlọ ti Gbọngan nşe ki gbogbo ẹnyin Ẹgbẹdọrẹ ki ẹ fi eti silẹ kẹgbọ.

Ipinlẹ Ẹgbẹdọrẹ sọ wipe awọn nfẹ niibusọ motọ. Agbọ lẹhinna pe ijọba nla fi owo bi apo bi marun silẹ şugbọn titi di oni oloni kosi ẹniti o mọ gẹgẹ bi wọn tise na owo na. Bẹni a kori ki wọn se ibusọ motọ na.

A tun gbọ wipe wọn fi n'kan bi apo owo marun silẹ lati fikọ lsọ ọja. Titi di oni oloni a kori kiwọn kọ isọ kankan bẹni ko si ẹniti o mọ bi wọn tişe na owo na bi o ba jẹ otitọ. Ni asiko ti wọn bẹrẹ işẹ yi ni Gbọngan ko ni Akọwe kotu, Loju tẹmi asiko ti awọn wọnyi ko dara fun Gbongan.

Ni akoko ti awọn wọnyi wa ilọsiwaju kan kosi ni Gbọgan afi irẹsilẹ. Eti ni wọn fi nmọ Ogiri lati le ma sọ ọran kekere di nla ki wọn ba le ma raye gba ibọlẹ.

Ọlọpa O! Bẹni ẹnyin sọ wipe ẹwa ni Odẹ-Omu nibẹ yẹn, ẹgbin ẹpa, ọ si tun fi ọmọ ikun bọ abẹ ẹri oju ole ọ ko mu.

Orişirişi ifẹhin-kẹhin ni wọn ti da silẹ larin ilu. Eyi olori wọn loda ifẹhinkẹhin silẹ ni Church C.M.S. ni Gbọngan.



APETU TI IPETU, AGUNBIADE KEJI

Nkan bi oşu kan abọ lo şe ni irin ajo rẹ lọsi ilu Oyinbo ati Amẹrika. O şe idupẹ fun dide ti on de pẹlu alafia ni ile ijọsin St. Paul Ipetu-Ijẹşa. Ogbẹni H. A Oluwasanmi na şe idupẹ lọjọ na nitori dide ti o de pẹlu alafia lati ilu Oyinbo lẹhin to ti lo nkan bi ọdun mẹsan lọhun.

---

## Ikede Ati Ipolowo Oja Ninu "IRAWO OBOKUN"

OJU EWE KINI

| | | | | | |
|---|---|---|---|---|---|
| Igba | 1—12 | 8s. | fun | inşi | kan. |
| Igba | 13—25 | 7s. 6s. | " | " | " |
| Igba | 26—52 | 7s. | " | " | " |

OJU EWE KEJI

| | | | | | |
|---|---|---|---|---|---|
| Igba | 1—12 | 5s | fun | inşi | kan |
| Igba | 13—25 | 4s. 6d. | " | " | " |
| Igba | 26—52 | 4s. | " | " | " |

OJU EWE KẸTA

| | | | | | |
|---|---|---|---|---|---|
| Igba | 1—12 | 7s. 6d. | fun | insi | kan |
| Igba | 13—25 | 7s. | " | " | " |
| Igba | 26—52 | 6s. 6d. | " | " | " |

OJU EWE KẸJỌ

| | | | | | |
|---|---|---|---|---|---|
| Igba | 1—12 | 6s. | fun | inşi.kan | |
| Igba | 13—25 | 5s. 6d | " | " | " |
| Igba | 26—52 | 5s. | " | " | " |

OJU EWE 4, 5, 6, TI 7 JẸ OWO KANNA PẸLU TI OJU EWE KEJI.

